136 Ìjọba Ọlọ́run Ti Ń Ṣàkóso —Jẹ́ Kó Dé!

(Ìṣípayá 11:15; 12:10)

1. Jèhófà, o ti wà tipẹ́,
   Ìwọ yóò máa wà lọ.
   O gbé ọmọ rẹ gorítẹẹ́;
   O pàṣẹ kó jọba.
   A ti wá bí Ìjọba náà;
   'Jọba rẹ̀ yóò kárí ayé.

(*ÈGBÈ*)
Ní báyìí, ìgbàlà,
Ìjọba àtagbára dé.
'Jọba náà ń ṣàkóso.
Jọ̀wọ́: "Jẹ́ kó dé, Jẹ́ kó dé!"

2. Àkókò Èṣù ti kúrú;
   A mohun téyìí jẹ́.
   À ń gbé lákòókò wàhálà,
   A ró'un táyé kò rí.
   A ti wá bí Ìjọba náà;
   'Jọba rẹ̀ yóò kárí ayé.
(*Ègbè*)

3. Àwọn áńgẹ́lì ọ̀run yọ̀
   Wọ́n sì fayọ̀ kọrin.
   Àwọn ọ̀run ti bọ́ lọ́wọ́
   Sátánì òpùrọ́.
   A ti wá bí Ìjọba náà;
   'Jọba rẹ̀ yóò kárí ayé.
(*Ègbè*)

© 2015 Watch Tower Bible and Tract Society of Pennsylvania

(Tún wo Dán. 2:34, 35; 2 Kọ́r. 4:18.)